# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI"—W. T. STEAD.

VOL. II. NO. 72. SATURDAY, NOV. 24, 1923. FOURPENCE.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware. Peer. Wine. Iron Bedsteads. Ruby Plates. Rubber Beds of all kinds. Clay and Briar Pipes. Champagne. Cement. Biscuits in cases. Gun Powder. Wire Nails Faugoon and original Ballam Rice. Accordeons. Piano. Padlocks. Beads etc., etc., etc."**

---

Ọgbẹni DURO THOMAS

Cnișowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

---

### N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7. Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.







Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikẹle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ọkọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni OGBẸNI na jẹ ninu awọn onisọwo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po ọ.

---

## B. O. Joseph

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**
**Sundries.**
**Hardware.**
**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

---

## The British Psychological Institute

OF BOLTON, ENGLAND,

teaches by Correspondence the following Sciences :—Psychology, Philosophy, Phrenology, etc., etc

For complete particulars, apply to the Official Representative of the Institute for Nigeria and Gold Coast Colonies

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos.

*Youngmen, for future's sake, be on the alert.*

## THE LAGOS HOTEL

Iced Drinks of every description on sale at the above popular Hotel.

Clients' comfort occupies a prominent part in the programme of the establishment.

Billiards playing forming a centre of attraction.

**TERMS :—Strictly Cash.**

H. H. KING
*Proprietor.*

Portonovo Market St.,
Lagos.

---

ILE ERO TI EKO.

Ohun mimu olomi didi to np'ongbẹ ẹnia nbẹ nihin lorisirisi fun tita.

Ko si ọna ti a ko ngba fi tẹ awọn onibara wa lọrun.

*Billiards* idaraya si wa fun ẹnikẹni lati ṣere. Owo-lọwọ la fẹ.

H. H. KING,
*Oni-nkan.*

Ita Ọja Ajaṣẹ, Eko.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

GBERE, ỌMỌ BALOGUN OGUNBỌNA AGBOKE-T'OYINBO.

O jẹ didun inu wa lati gbọ pe awọn Agba Ijọ Arọlọva npete ati ṣe Awowo kan nipa jaba fun Baba wa nipa ti Oluwa Bishop Howells ni Ile Ijọ na ni ọtunla. Ẹ kare, ẹnyin enia to mọ iyi to m'ẹyẹ.

Ẹ KU'RIN ỌBA ALAIYE-LUWA.

A gbọ pe Akarigbo Ọba Ijẹbu Rẹmọ de sinin lati Iṣagamu ni *Saturday* to kọja, lun Fāji ati pe Ile Ọgbẹni Rufus Wright Ologbe ni ita Joseph lo wọ si; Abọ o!

ERE IJE KURO LAWADA.

Awọn Ọgbẹni Ransome-Kuti Olori Ile Iwe Giga ti Ijẹbu Ode, Ṣowunmi, Lucas ati awọn ẹlomiran bẹrẹ idanwo wọn ni Ịọlọyi fun oye Diakoni ati ti Alufa kikun ni Ijọ wọn—C.M.S. Orire niti awo.

CHARLIE ỌRẸ MO GBADUN RẸ, EGE LO YẸ CHARLIE.

Ihin kan ni lọṣẹ yi pe a pe Ọgbẹni Charles Ọbafẹmi si Awo iṣẹ *Lawyer* ni Ilu Oyinbo ni *Monday* ọjọ kọkandilogun oṣu yi. A ba baba ọrẹ wa na Daddy Harrison Ọbafẹmi, Ọgbẹni Michael Ọbafẹmi ti Ile owo G. B. Ollivant ati A. A. Ọbafẹmi, Ajiya boto-ninu-aworan yọ fun iṣagunmolu ọmọ ati aburo wọn yi.

ẸNYIN IGARA OJU OMI, Ẹ O JOYE APẸLẸWỌN BI ỌBỌ LAIPẸ.

Diẹ ninu awọn ero Ọja Ọjọ sọ fun ni lẹdunṭẹdun pe iwa jamba ti awọn ole ati Igara kan nhu si pupọ awọn ero Ọja lapa Ọja yi ni Abuleko kan kuro ni ṣereṣere. A sọ pe ni a'pẹ yi, awọn ole na lọ ko ile Ọgbẹni kan loru, nwọn si fā aya Ọgbẹni na lori korodo, tobẹ ti obinrin na fi dabi Afari korodo agba Ijẹbu a'sọ pe titi awọn ole yi fi nṣe eyi, fọ'fọn niti fọn ni obinrin na sun ati awọn ara ile na; nigbati ilẹ mọ tan ni ariwo sọ lẹhin igbati awọn ọlọṣa na ti lẹ kito.

Ẹnyin Opa Ọba, ẹ jigiri ati wadi ọrọ yi o, ki ẹ mu si jatara ati dabobo awọn enia wọnyi ni igberiko ọja na.

Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

*Editor* "Eko Akete" nṣete ati ṣe Ipade gbogbo-gbō ti Ilu ni Ile Afari Ọgun (Ile Ẹgbẹ l'Ẹbhingbẹti) ni ọjọ Atini (*Monday*) ọtunla ọjọ 26 oṣu yi ni agoṣo mẹrin-abọ aṣalẹ lati sọ ti iranlọwọ ti o nfẹ lọwọ ilu nipa ilọsiwaju Iwe Irohin na.

A pe t'ọmọde t'agba t'ọkọnrin t'obinrin sinu Ipade yi.

Ọgbẹni wa J. A. Oṣodi Alaragbayida Ayọ-ninu Ẹgbẹ daradara ti 36 Ita Idoluwo Oniṣowo, ni yio ṣe Alakoso Ipade na.

A tanmọ pe ẹṣẹ gbogbo awọn to ti nka Iwe Irohin yi ni akagbadun lọṣọṣẹ lati iwọn oṣu mẹdogun ti a ti bẹrẹ rẹ, ni yio pe pererere si Ipade yi.

ABỌ O!

Pastor A. Adedeji Iṣọla ati diẹ ninu awọn *Member Church Brotherhood* ti nwọn ti lọ si Ijẹbu Ode fun Iṣe *Mission Church* na ni Ịọlọyi, bọ wa'le ni alẹ ijẹta; Alafia k'ẹ de?

ARA FẸ JOJO.

A gbọ pe Alufā S. J Gaunsilo ti Ijọ Ebute Ero, gba isinmi bi ọsẹ mẹta lẹnu iṣẹ rẹ; ni gasikiya, iwọn-tún-wọn-si ni iṣẹ fẹ.

## ỌLỌMỌ LA.

O ta si ni leti fẹnrẹn pe Bishop Howells ati awọn Ẹbi rẹ yio ṣe iranti ọdun kan ti Iya wọn ti tẹrigbaṣọ ni Ọjọ kinni oṣu *December 1922*, ni Abẹokuta; nwọn o ṣe iranti ọjọ nã ni ọjọ kinni oṣu *December*, to nbọ yi. A kã mã reti Páki na? Ki Baba mu ọjọ ro.

## KILOKAN "FATOLU" ỌYỌJU ỌRAN?

A ngbọ kakiri nibi gbogbo pe awọn obinrin Kiriyo Oniyẹri kan joye "Ṣọbọṣọla" nipa lilọ sodọ Ijọba ninu ọsẹ yi lati da si ọrọ awọn Imale; bi o ba jẹ pe awọn ti a wi wọnyi fi ọtọ inu lọ ṣe irufẹ iṣẹ bayi ni, a ba "yonbo" wọn: ṣugbọn gẹgẹbi a ti mọ wọn si, ati ọrọ wọn, rúgúdù kan ni nwọn tun nwa ọna lati da silẹ. Ikoko dudu ko gbọ ti ara rẹ o ngbọ ti ẹnikẹni!

## O TORI AJA, AKARA D'EGUN.

A gbọ finrin pe awọn Oyinbo ti o nkọ awọn enia ni iṣẹ Lọya ati ti Dokita ni ilu Ọba, ti bu si ọdun ti a ti fi nkọ iṣẹ na: gẹgẹbi a ti so fun ni; a sọ pe ẹniti o ba fẹ lọ kọ Iṣẹ Lọya lati ọdun to mbọ, yio ni lati wa ni Ilu Ọba lati kọ iṣẹ na fun ọdun marun dipo ọdun mẹta ti a ti nfi kọ ri, ati ọdun mẹjọ gbako fun kikọ iṣẹ Dokita dipo ọdun mẹfa tabi mẹfa abọ ti a ti fi nkọ. Ọrọ re o!!!

## ALHAJI ONINURE, ORUN RERE.

A kẹdun iku Alhaj Alli Fahm to sẹ'lẹ ni Alamisi (*Thursday*) ọsẹ yi ni ile rẹ ni ita Oluwọle, ki Ọlọrun f'ọrun kẹ.

## AFÃ ṢỌṢI, Ẹ DAKẸ NI?

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo juba o,

Ki ọtun wẹ osi, ki osi wẹ ọtun ni ọwọ fi nmọ, ṣugbọn nigbati ọran ba oju, ti imu nhu iwa "A don kia" (*I don't care,*) igi ko da baun? Irufẹ iwa "A don kia" yi li o si dabi ẹni wipe awọn Afã Ṣọṣi nhu nigbakugba ti rudurudu tabi Idamu ba de si ilu.

Pupọ ninu wọn ro wipe nigbati on ba fi ṣe iwãsù meji lori igi (*Pulpit*) li ọsẹsẹ, ti on si ṣe Kilasi (*Class*) fun wakati kan li ẹmeji tabi li ẹmẹta li ọsẹ, on ti pegede; ki oṣu pe, ki on si gba owo iṣẹ on nikan li o tun ku. A gbọ wipe nwọn ki gbe Iyawo fun enia l'ofẹ li aigba "Obi," bi obinrin ba si fẹ dupẹ ewu Ọmọ-bíbi, o ni lati di "ẹgẹ" rúgudu fun Afã. li aika owo pẹ-pẹ-pẹ miran ti ngba ọna pupọ bọ si inu ajufu wọn, bẹni ẹ... "Jesu ko gb'owo, Jesu ko gb'obi" ni Kirikiri nkọ li ojojumọ.

Lati ọjọ ti Alaiye ti da aiye ni ẹniti o ba ṣe, ti lati jẹ, enia ko si le ṣe iṣẹ Afã d'igbese. Lọ... temi, awọn Afã Ṣọṣi dabi Olnṣọ-agutan ti o ni lati jẹun ti ara ati ti ẹmi yó daradara, ki nwọn to le toju Agbo-agutan won gẹgẹ bi ilana Kristi. Bi Bibeli ati adura ba si to fun onjẹ ti ẹmi—onjẹ ti ara nfẹ Kọrẹnsi (*Corrency Notes*) ti o dan.

Nitori idi eyi ni a ko ṣe le da Afã ki Afã fi ẹbi fun asiki owokowo ti Ọlorun ba pese fun wọn li ona ti o to; ko nṣe wipe ki a da owo si wọn lọwọ bi igbati a mu nkan fun Afala, ti Afala fa a la. O dabi owe o.

Tani le fi ọwọ so àiya wipe lati ojo kanna ti ... ti de aiye li on ti nṣe iṣẹ Afã, tabi ki o leri wipe bi o tilẹ jẹ wipe on ti balaga tan ki on to ga Agbada pelu Kọlà K'ẹhin-s'aiye (*Clerical Collars*) o da on loju gbangba wipe ninu iṣẹ na li on mu ku si, ko si; bẹni gbogbo wa patapata li o le ... ògún gba'ri wipe lati ọjọ ti a ti de inu aiye li a ti nṣe ara ilu—ara ilu na li a o si ma ṣe, titi ọjọ igbende Alikioma. *Halá yao mal Kiyamat.*

Bi oyè ara Eko kan ninu iṣẹ Afã pọ ju ti Archbishop of Canterbury ti ilu Oyinbo lọ, eyini ko ṣe oloyè nla na di Oyinbo, ara Eko li o jẹ sibẹsibẹ. Ṣọṣi Eko li o ma ṣe iwasù, owo Eko li o ma fi ra ata pẹlu alubọsa ni ita Faji ati Ereko, dukia Eko li o ma fi ṣe ọlá; nitorina, ko yẹ ki o hu iwa "A don kia" si ọrọ Eko, ko si tọ ki o gbàbọdi tabi ki o fẹ apakan ilu, ki o si yan apakeji ni ipọsi.

Bi ara ilu ko ba le, ailera na yio ran Ṣọṣi. Ṣọṣi wo ni a ko ti ilẹkun rẹ nigbati àrun ayọkẹlẹ nba ilu ta iporogan li ọdun karun ti o koja; Ṣọṣi wo ni ko fi ara gba li akoko ogun ajakaiye, tabi Ṣọṣi wo ni ko ṣe gbẹdẹ fun li akoko ti awọn boys nlẹ Kọrẹnsi mọ lady li àiya, ti awọn kan si nra Burẹdi Aganyin oni-tọrọ (3d.) ni pọnwun meji-abọ (£2 10 0) ati aja (dog) kekere kanṣoṣo ni pọnwun meje-abọ (7 10 0) ni Ikore Ṣọṣi.

Ṣọṣi hu iwa "A don kia" si ọrọ *National Congress of British West Africa*, si ọrọ *Criminal Code*, si ọrọ *Provincial Court Ordinance*, si ọrọ Eleko, si ọrọ Lọya ati Dokita enia dudu ti ko si ni ipo ti o dara to ni iṣẹ Ọba, si ọrọ Afa enia dudu ti ko le di Bişọpu kikun bi Oyinbo, ani ju gbogbo rẹ lọ.

# EKO AKETE.

Eko, Saturday, November 24, 1923.

## ỌLỌRUN NI YIO GBA ABUDULAI LOKO OLOWO.

### IMALE KI SINGBA.

Ọrọ yi ni a le sọ si ti gbun-gbun-gbun to wa nisinsinyi nipa ọrọ Imale, a si fẹ ki awọn ọkawe wa ṣakiyesi ọna ti a o gbe ọrọ na gba ninu Iwe Irohin ọsẹ yi. Ibere mẹta si ni a fẹ bi ara wa ki a to fi idahun wọn si i.

Ekinni :—Tani a pe ni Abudulai ninu awọn Imale ilẹ yi ?

Ekeji :—Kini Oko Olowo ?

Ẹkẹta :—Kini Igba sisin ?

Awọn Abudulai ni awọn Janmã ti nwọn ko sinmi, ti nwọn ko baye lati fi gbogbo nkan Isin nwọn si niginnigin nipa yiyan olori pataki-pataki ninu nwọn fun ati bojuto ona Isin ; awọn Musulumi wọnyi jẹ ọpọlọpọ ninu awọn Imale to mbẹ ni ilẹ yi. A gbọ pe ninu Mọṣalaṣi bi meji-dilogoji to wa ni ilu, awọn Mọṣalaṣi mẹrinlelọgbọn lo wa ni tiwọn, ati pe Mọṣalaṣi mẹrin pere to ku lo lodi si wọn ; bi awọn Janma yi ba si wariko fun mimu ọna Isin wọn si ẹ̀tọ́-tọ̀rọ̀ kilopo ? Ṣugbọn o dabi ẹnipe awọn kan wa ti nwọn jẹ Imale bakanna ti o wa njẹ didun inu wọn nigbakugba lati ma ru awọn enia soke fun ija, dajudaju awọn wọnyi ko fẹ ki alafia ki o wa larin gbogbo Imale ; nitoripe ọna ati ma da won si meji ni irufẹ awọn bayi ngba nigbagbogbo ; nigbati a sorikodo ti a nwõ, o dabi ẹnipe pupọ ninu awọn wọnyi ni ko niṣẹ lapa ti nwọn ko labọ lesẹ, bikosepe ki nwọn ma yajule awọn àgbà kiri lati ma gbe ọkan wọn gbona nipa sisọ ohun ti ko si : ni ọna bayi,* ija Imale ti iba ti pari lati ọjọ jọjọ si nbi si siwaju.

Kini oko olowo jẹ ?

Oko olowo ti a ni Abudulai wa ko ju gbigbun ti awọn ti a nwi wọnyi ngbe awọn Janma na gbun Ijọba loriṣiriṣi ọna lọ ; bi awọn Janma sõ tẹ̃n, bi nwọn tọ ya o di ki nwọn fi ẹsẹlẹsẹ lati lọ sọ fun awọn kan pe eti rẹ melo ? Onitọhun a ni meji nwọn yio tun bi pe kilo fi ngbọ? Oni-tọhun yio tun dahun pe, ọrọ ni ; nigbana ni nwọn yio sọ ohun to ṣe sọ, ati ohun ti ko ṣe sọ, lati lẹdi awọn enia wọnyi lẹhin wọn ; o si daju pe Ijọba ki nṣe agiwere lati gbọ ẹjọ ẹnikan da ; nitoripe bi nwọn ba wa idi rẹ siwa-sẹhin, fùlúlú ni iru ọrọ na nja si.

Kini Igba sisin ?

Igba sisin ko ju hilahilo ti irufẹ iwa ti awọn alapamaṣiṣẹ wọnyi nhu nfi awọn Janma na si lọ, bi awọn Janma ba si f'ọkan sibikan lati tẹnumọ kunkun pe ọrọ Isin yatọ si ọrọ ilu, a tanma pe a o fẹ mu wahala yi ku.

Jijẹ ti a fi Ligali jẹ Lemọmu-Agba ni ọsẹ diẹ to kọja, jẹ ọrọ Isin, ko si eyi ti o kan Ijọba nibẹ ; a le fẹ fi enia joye *Bishop* ni Ile Isin Ijọ Ọmọ Ibilẹ, ki a ṣeṣẹ lọ ṣe jeje korodo iyẹn lọdọ Ijọba bi ? Agbẹdọ ! bi elegun ngbe egun, ti oloriṣa si joye Arọbadade, ti o si nyọ ina lẹnu bi Ṣango lọna Isin rẹ, Ijọba ki yio ni o kun tabi o ṣẹku niwọn igbati iru Isin bẹ ko ba ru ofin kan, tabi ki o pa ẹnikẹni lara ni ilu : nigbakugba ni a ti nsọ sinu Iwe Irohin yi pe Araba nla ni Ijọba Gẹsi jẹ fun gbogbo awa enia to wa labẹ wọn, nwọn ko si ni ki ẹnikẹni maṣe ohun ti o fẹ niwọn igbati ohun bẹ ko ba lodi si ofin ; bi ogun oniṣ ko togbọrọ oni-kọ̀ à kan, ti o si fari oriṣa lọsangangan, ti o si nla ilẹ ni ipa wọnin, ti o nja ijo Ṣango, Ijọba ki yio bere ohun to nṣuta. A lẹ ki awọn enia wa ki o mọ eyi, ki nwọn si dẹkun a nko jọnin jọnin ba ẹnikẹni ninu Isin.

O ta si wa leti fẹnrẹn pe awọn Ọgbẹni Herbert Macaulay ati J. Egerton Shyngle ti nlọ soke lọ sodo ni lọlọyi lati pẹtu si ọrọ a jẹ Lemọmu a ko jẹ Lemọmu ti o di iyọrọ ti o bo awọn oni-jagidi-jagan

tan nisisiyi. Adura wa ni pe ki Baba na ṣai fun won ṣe.

Akoko to, ki olukuluku fi tirẹ ṣe tirẹ, ki enikẹni si ye joye Bisi Bẹke Aluojubọ.

K' Ọlọrun ma ṣai gba Abudulai loko olowo, Imale ki nsingba!!!

---

Si Oni'we Irohin EKO-AKETE
Lagos.

Mo bẹrẹ f'oji o.

Mi o le ma fi ẹnu sọ nipa iṣiri ti mo nri nipa kika Iwe-irohin rẹ. Ki Ọlọrun Olodumare ninu anu Rẹ nla ki o ma ṣọ ọ, ki o masi ṣe jẹ ki o ri itiju—Amin ati Amin.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awọn alagbara ngo si jẹ alagbawi awọn odi"—W. T. Stead.

Ọrọ yi ni ohun ikini pataki ti o dabi ẹni pe o nlu ilu fun mi wipe "dide jo." Mo ro pe ọrọ ti mo fẹ sọ na, nigbati mo ba nba lọ ẹ o ri dajudaju pe, Malu ti ko ni'ru ni.

Gẹgẹ bi a ti ri ka ninu iwe Irohin rẹ nipa Alufa o ni ṣokoto gborọ ti o lọ gba iwe ipa (*Fi fa*) lati mu onigbese rẹ, gẹgẹ bẹ ni Alufa oniṣokoto gborọ kan ṣe ni Agbadarigi ni lọwọlọwọ yi. Alufa po ni Agbadarigi nisisiyi loto, ṣugbọn bi a ba wipe mọ o, ọmọran a mọ ọ. O ti ṣe ki! nikun Alufa na nisisiyi. Ki nto ma ba ọro yi lọ siwaju, o ye ki a ka *Psalm 50 Verse 21*. "Nkan wọnyi ni iwọ ṣe emi si dakẹ, iwọ ṣebi emi tẹle dabi iru iwọ tikarare; ṣugbọn emi o ba ọ wi, emi a si ka wọn lẹsẹsẹ l'oju rẹ."

Alufa ti mo wi yi fi iwe (*Letter*) ran awọn ọmọ kan niṣẹ si Eko (*Lagos.*) O si wi fun wọn pe ọgbọn ṣile wa ninu iwe na, ati pe nwọn ni lati mu *letter* na lọ fun Iyawo rẹ loke odo. Bẹni awọn omode na ko mọ Eko tẹlẹ, bẹni nwọn ko mọ ile Iyawo re ti o ni ki wọn mu iwe fun. (Ki ẹnyin enia Ọlọrun jọwọ kiyesi iru iwa yi daradara o.) Enia ti ko lọ si Eko ri, ki a fun ni iwe (*Letter*) pe ki o ba ni mu lọ fun Iyawo ẹni ti o jẹ pe ko si ni Eko papa. Ka to wọkọ de Eko, ka sọkalẹ lẹhinbẹti, ka wa fi ẹsẹ ṣa lọ titi, ka ma sa fun moto (*Motor*) ka ma sa fun kẹkẹ (*Cycle*) ka to sa fun ẹṣin, ka wa lọ gun ori kereni Iddo. Ka tun jiya jiya titi ka sọkalẹ ni Iddo, ka wa mu ọna Ebute Mẹta pọn, ka wa ma bere, lọwọ t'aja t'ẹran pe, ẹ ku onile, ẹ mọ ibiti aya Alufa gbe wa fun mi? Enia ti ko wa s'Eko ri la ma bẹ ni iṣẹ agbara bayi o. Njẹ bi enia ko ba jẹ ẹniti o mọ oju ilẹ dara-dara, o gbọdọ daba ati lọ si Ebute Mẹta?

Awọn ọmọde wọnyi sa ipa lati le fi iwe jiṣẹ fun aya Alufa, ṣugbọn ọna jin. Bẹni nwọn ko tilẹ ri enia mu wọn lọ. Njẹ ki o ma jẹ pe nwon ṣe alai jiṣẹ, nitorina nwon lọ ra Ontẹ (*Stamp*) wọn si lọ fi iwe na ranṣẹ. Nigbati nwon pada bọ wale ti nwọn sọ fun Alufa oniṣokoto gborọ ti o npe ara rẹ ni enia Ọlọrun nko? O gbọ bi o ti wi? O ni bi Iyawo on ko ba ri owo na gba, ki awọn ọmọ kekeke mọ daju pe wọn o san a pada. Laifa gun lọ titi Alufa oniṣokoto gborọ ma gba owo na lọwọ wọn o.

Mo ni Alufa kanike gba owo na perepere lọwọ awọn ọmọde na o b'omi ṣin wọn lọwọ, o si tun la'nu mẹnrẹn pẹlu. Eyi ha dara? Ọlọrun Ọba ariwa-rẹhin lo le jeri awọn ọmọ na, nitori a ko mọ inu wọn. Sibẹ-sibẹ o ha tọ fun ẹniti a pe ni Alufa lati hu iru iwa ọmọ aijọbẹ ri bayi? Alufa tori 30/- ba orukọ ara rẹ jẹ bayi. Bi a ba nṣe bayi si igi tutu, bawo la o ha ti ṣe si igi gbigbẹ? Ọtọtọ awọn eleyi jẹ ọmọ Ijọ niyi o. Bi o ba jẹ ọmọ Abọriṣa tabi Imale kan ni, mo ro pe kanike yi ko ni kọ ki a ti awọn ọmọ na mọle. A! ẹnyin ọrẹ mi njẹ ohun ti o ti ni loju ju ole lọ ko si baun? Dajudaju o wa. Awọn ọmọ na san 30/- orukọ wọn ko pada. Oju ati Alufa olowo yi nisisiyi lati le ma ki awọn ọmọ na.

Alufa yi ma nṣe iwasu nipa awọn owe Jesu Oluwa wa ti o pa fun awọn ọmọ ẹhin rẹ nipa onigbese ti oluwa rẹ dariji.

Ṣe apẹrẹ ni iru nkan wọnyi jẹ fun onigbagbọ Alufa Agbadarigi ti tori 30/- ba iwasu rẹ jẹ. A! o buru, o buru, o tun buru o ju gbese lọ. Ko tilẹ daju pe Alufa na tun ranti iru ẹjẹ ki o to gba kola. Bi Alufa yi ba mọ pe on fẹ lati jere enia fun Kristi ki o maṣe ṣe bẹ mọ.

Nitoripe o ṣoro fun ole lati ma wasu fun enia pe ki o ma jale mọ, nigbati o jẹ wipe ọlọṣa, wompari, kolekole ni on papa. Alufa yi ni ero pe kini wọn mọ l'agbadarigi, ṣe ara oko ni wọn.

A! O maṣe o, mo kãnu fun Alufa na pupọ pupọ. Mo bẹ Alufa yi ki o maṣe wo pe mana-mana ko rọrọ ki o fi ma t'ika bọ lẹnu. Gambari ko m'ole'ja oluwa Gambari ni nkọ Gambari l'ole yi o. Diẹdiẹ ni awọn Alufa bawọnyi yio ma fi ara wọn han fun awa Egun pọn-pọn. A bẹ Alufa yi, ki o yara lọ fi owo na ra ilẹ amọkoko, nitori iru owo bẹ ti di 30 owo fadaka ti Judasi gba ni ọjọ kini. Bi bẹ kọ, ki o yara dijn sọ owo na si ọsa tabi ki o fi tọro fun awọn alagbe lẹhinna ki o lọ tọrọ aforiji lọdọ

Ọlọrun ati awọn ọmọ rẹ pẹlu. Ki o ma lọ ki o ma si tun d'ẹṣẹ mọ ki iru ohun ti o ju ti eyi lọ ki o ma ba wa ba.

Emi ni tirẹ nitotọ,

SEKARIA—*Woli.*

---

## ỌKỌ A RE FO!

Si Oni'we Irohin "EKO AKETE"

Mo juba o,

O ta sini leti wipe Ẹni-ọwọ I. O. Oyekunle ati Ọgbẹni M. O. Allen (Alufa ati Baba Ijọ Eletọ Ọmọ-Ibilẹ) pẹlu arakọnrin wa Ọgbẹni Akinyẹmi Amosu nlo si Ajido fun iṣẹ Ọlọrun larin awọn Abọriṣa ati Imale ti o wa ninu ilu yi.

Ki Olodumare ki o la oju awọn enia wa wọnyi lati le sin Ọlọrun Alaiye lai ṣe agabagebe. Aṣẹ.

A o jihin abọ wọn lọsẹ to mbọ.

ALỌMA-VI

---

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Ma ṣai fun mi li àye diẹ ninu Iwe-irohin rẹ ọsẹ yi, lati ba so ti ẹnu mi fun awọn ti o ba nfẹ ilọsiwaju ilẹ wa nitotọ.

Ọmọde ni mo jẹ, ng ko si ni ogbọn tabi oye tó lati fi rú ifẹ awọn enia wa soke to bi mo ti fẹ, ati bi o ti wa li ọkan mi. Ohunkohun ti mo ba sọ, bi o tilẹ je ogbọn omọde ni mo fi sọ o, ẹ gba a bẹ, ki ẹ si sọ o di ki un ati pipé ninu nyin; ābọ ọrọ li a sọ fun ọm luwabi, bi o ba de inu rẹ li o ndi odidi.—(Owe ẹnyin agbalagba o.)

ẸNYIN ỌRẸ, EKO, ATI ARA ILU, Ẹ YA MI L'ETI NYIN.

---

Ninu gbogbo ilu ni Nigeria, Eko ni aṣiwaju, ninu gbogbo nkan; funọgbọn, ọmọ'we, oni'po ati olowo to o wa ninu rẹ: a ko si fẹ awọn ọpe, alaimọkan ati awọn alābọ-ẹkọ kù ninu rẹ pẹlu lọpọlọpọ. Awọn w ny. ni ireti lori, ti a ba le fun won ni anfani akanṣe, eyiti nwọn ko ri àye rẹ li ọmọde.

Mo ke pe ẹnyin Baba wa, ni ọmọ'we, ni ọjọgbọn ati olowo, lati gba a ro wipe ki anfani le wa fun iru awọn wọny, ti o jẹ wipe, yala aini enia tabi owo to, nwọn ko le ni ẹkọ ti o ye kòro, ti a nke igbe rẹ li Eko nisisiyi, anfani na ni ti Ile-iwe alẹ (*Evening Class*) fun awọn Oṣiṣẹ, tabi awọn ti o ba fẹ lati lo, ati lati jẹ anfani na. Tali o mọ ohun ribiribi ti o maṣe li arin wa; Ile-iwe alẹ ṣe awọn Oyinbo li ōre, o si nṣe wọn li ōre lọwọ bi a ti nsọ yi: mo le tọka nyin si meji tabi mẹta ni awọn Oyinbo ti Ile-iwe alẹ ti ṣe li ōre. Enia bi Dr. Okey, ẹniti o jẹ wipe ni igbati ko, ẹniti o ma ran a lọ si Ile-iwe, o lọ kọ iṣẹ hwun'ṣọ (*Apprentice Weaver,*) nigbati o ṣe, oy ri lo fẹ o si di Igba-keji Ọga Awunṣọ (*Assistant Weaver*) Ninu owo ti o ngba bi ṣile kan ābọ (1/6) li ọsẹ, o fi nra iwe a-lo-kù ti o nkọ; nigbati o bẹrẹ Ile-iwe alẹ, ti o fi ori ti iṣoro rẹ, o gba oye *Doctor* o si di *Professor University* kan fun ede Italy (*Italian.*) Bẹ na si ni ti Ọgbẹni Jackson Coleman ti o jẹ wipe Ile-iwe kekere li o lọ, lẹhinna li o bẹrẹ ti alẹ, o si fi ori ti i tobẹ ti o fi di *Lawyer* loni. Ti awọn wọnyi dun; ẹ gbọ ti Ọlọpa kan ti Ireland, ti o njẹ Patrick Smith, nipa āyan ati iforiti ni Ile-iwe alẹ, o di Oloye M.A. (*Master of Arts,*) eyi ko tẹ Ọlọpa yi lọrun, o ni afi bi on ba gba oye *Lawyer* pẹlu; o mu ileri rẹ yi ṣẹ laipẹ, nwọn si "pe e si Agbo" ni Dublin. Ẹgbẹ kan ti a npe ni "*Workers Educational Association*" ati "*Ruskin College*" fun awọn Oṣiṣẹ li o nṣe ohun àra bayi; melo li a ma ka ninu ehin Adepele, ti inu ọrun, ti ode ọjọ, ojile-nirun li o fi ori mulẹ li aiyọ, ni ti awọn enia ti o ri ōre Ile-iwe alẹ gba je, ki a dakẹ lotọ nipa awọn yen. Bi a ba le ri iru anfani bi eyi ni Eko, aiye wa iba tòro ju bayi lọ, a ba bọ bibo. Ẹnyin Baba wa, ẹ ma ṣairi wipe anfani bi ti Ile-iwe alẹ wa fun wa ni Eko, ki a si ri Ẹgbe bi "*Workers Educational Association*" ni Eko, bawo li o ti ma dun to!

"EKO AKETE," iwọ ti o sọ wipe:—"Ohun ti o ndun Makunnu li o ma fi nhan awọn alagbara," iṣẹ na ya way ;nitori o to akoko ki Eko ni anfani yi kun eyiti o ti ni ri. Mo ni igbagbọ wipe ọrọ mi yi, bi ko ti pọ tiy m-tivan yi, ẹ ki yio jẹ ki o bọ si ilẹ gbigbẹ li ọkan nyin. Ki Ọlọrun ma ṣai fi diẹ na ṣe iṣẹ nla fun ire ilu wa o.

Mo dupẹ fun àye ti o fun mi yi.

Emi ni tirẹ,

AGBORO-ỌDẸ.

[A fẹ ki awọn Ọkawe wa ṣe akiyesi ọrọ ọgbọn ọdọmọde'kọnrin yi. Ọgbọn ko sa si ninu Irungbọn-hihu.

*Editor,*—"EKO AKETE."]

### TOWN WARDEN, TO THE RESCUE !!!

We would very earnestly call the serious attention of our Town Warden to the neglected state of Upper Williams Street, on your way to Taiwo Street as you leave the public Fountain. It is usually the practice of the scavengers detailed for duty in this part to turn up AT THEIR SWEET WILL in clearing the drains, with the result that filth gets accumulated from day to day to the inconvenience of the rate-payers: the effluvia emanating from this dirt can be better imagined than described.

Will the Town Warden please note.?

## NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

**LAWANI BAMGBADE LAYENI,**

**(Deceased.)**

*Pursuant to the Statute 22 & 23 Victoria, Chap 35.*

NOTICE IS HEREBY GIVEN that all creditors and other persons having any debts, claims or demands upon or against the estate of LAWANI BAMGBADE LAYENI, late of No. 75, Broad Street, Lagos, Nigeria, who died on the 4th day of September 1921, intestate, and Letters of administration of whose personal property were granted by the Supreme Court of Nigeria to the undersigned, are hereby required to send in particulars of their debts, claims or demands in writing to us at 4, Layeni Street, in Lagos, aforesaid on or before the 31st day of January 1924, after which day we will proceed to administer the estate and distribute the assets of the said deceased amongst the persons entitled thereto, having regard only to the claims and demands of which we shall then had notice and that we will not be liable for the assets of the said deceased or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose claim or demand we shall not then have had notice.

And all persons indebted to the said estate are hereby required to make immediate settlement of their account.

Dated at Lagos, this 24th day of October, 1923.

AKIN: ADESIGBIN,
IMORU LAYENI,
*Administrators.*


## AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, Williams Street Lagos.
*Residence* :—135 Igbosere Road.

**Charges Moderate.**


### POOR DELUDED "MOG" !!!

The coward "H. Adu Mog" who bursts forth in the issue of *The African Messenger* of the 15th instant (which, by the way, did not come to hand until the morning of the 21st instant almost a week late) in disgracing the columns of that paper by his trashy letter therein ought not to take leave of his senses as he has done in that discreditable missive. It would certainly have saved him much waste of stationery had he taken the least trouble to reflect on what the Celebrant in the Ahmadia Marriage Ceremony at Empire Hall was reported to have told his audience *apropos* of Muslims, and the Public house sometime ago; the Coward was misinformed when he attempted to palm it off on the public as true a marriage of a member of the Church of the Brotherhood at Ilupesi Hall, whilst his aspersion on us moves us to commiserate this misguided soul whose sole delight, it appears, is to muddle up matters rather than to sift them.

This scribbler ought to know though he pretends otherwise that it is Never an Article of Faith with us, to slam the door of our journalistic house in the face of any religious persuasion in this country, nor are we intolerant in our religious views a cursory glance at the weekly Table of our "Preachers for Tomorrow" in which even this Coward's Denomination—Ahmadia—prominently figures week in, week out, and that with no consideration whatsoever will convince an out-and-out fanatic.

Editor—*Eko Akete.*

## *IN MEMORIAM.*

In sad and loving memory of our dear beloved father,

ISAAC D. BICKERSTETH

Who departed this life on the 21st day of November, 1920, at Edea-Cameroon.

"'Tis three years since we missed thy loving face,
But aye! Thy memory lingers
Day by day the voice saith come
Enter thine eternal home."

"The saints of God! Their wanderings done,
No more their weary course they run
No more they faint, no more they fall,
No foes oppress, no fears appal
O happy saints! for ever blest
In that dear home, how sweet their rest.

BY KẸNKẸ.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo ikoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. I. O. Ransome-Kuti |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rt. Rev. Bp. I. Oluwọle |
| 6.30 p.m. | | (In charge) |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. J. Allen Angus |
| 7 p.m. | do. | „ D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Ereko | „ E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | „ S. A. Pearce |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | „ F. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | „ E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. Dan. Mould |
| 7 p.m. | do | „ Samuel O. Taiwo |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. M. B. Newton |
| 7 p.m. | do. | „ J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | „ do. |
| 7 p.m. | do. | „ G. A. Oke |
| 9 a.m. | Bethel | „ N. J. D. Shomuji |
| 6.30 p.m. | | „ J. A. Wright |
| 9 a.m. | Zion | „ E. A. Akinola |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. J. K. Ṣowọnlọla |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. J. A. Oshodi |
| 4.30 p.m. | | „ L. A. Randle |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. O. Fadipẹ |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 5 p.m. | | Bro. Joseph Adekọya |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | Bro. S. M. Phillips |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi | Bro. Arinola Ibaru |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Isẹh |

**St. STEPHEN'S (EPETEDU)**

9 a.m. & 4 p.m. Rev. A. Adekọya

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

| | |
|---|---|
| 10 a.m. | Capt. A. A. da Costa |
| 7 p.m. | Lieut. Colonel Geo: H. Souter |

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. F. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS**—EKURO.

Bi awọn oyinbo i'le-ọ̀wọ̀ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product.

£13—£14 fun *ton* kan

EPO.

£24—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£14—£19 fun *ton* kan bakanna.

**KANO**—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—£10 10 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**

9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

***Wool, Wool, Wool. Silk, Silk, Silk.***

Wulu tabi Siliki lo nfẹ ra ọmọ iya mi? Lọ si Ṣabu Iya Labu, nibẹ ni iwọ yio ri ni orisipe, Wulu ati Siliki lo fi ṣiṣẹ ṣe—Kọbọ ẹru.

( Abulati mbẹ pẹlu bi tẹdi, ọmọ iya Siliki ni. )

18 & 137, Victoria Street.

ẸNIKEJI,

Aṣọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

FOR SALE

One upright grand Iron-frame Piano, with beautiful tone. New condition—Owner going on leave, and will repurchase on his return six months.

For Terms, etc., apply to the EDITOR.

JUST THINK OF THAT.



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

**The Union Night School.**

FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge, Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor) For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati oṣiṣẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati ṣe idanwo fun iṣẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nṣe Ile-iwe yi'ni ọjọ *Monday*, *Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* ( Loke. )

Cable Address :—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18,
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

---

ẸGBE OYINBO ONISOWO
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16, 18, GERMANY.

Jẹ awọn onişowo ti ile Enia Dudu, nwọn ma nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ, ibaşe Ọja ti ilu Gẹsi tabi ti awon Ilu Oyinbo miran ti o wa lagbegbe *England* ati *Germany*.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si ilu awon Oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi Ọja-koja ranşẹ si wọn lati Eko tabi ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awon Oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Oba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-iti Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) l'Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK, Hamburg.

---

**CHANGE OF NAME.**

I, Moses Richard Affun, Sanitary Inspector Ondo, will be known as from the 1st of November, 1923, as MOSES RICHARD AFFUN ADEGBULU.

All documents bearing the former name prior to this date, of course remain valid.

**JACOB AJAYI,**
*General Woollen Trader,*
has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos,
***Prices to suit everybody.***
*Call now, fortune awaits you.*

---

OGUN YANMUYANMU ATI
EŞINŞIN.
(*Fly Catcher.*)

Eşe ti o fi rjẹ ki Yanmuyanmu ati Eşinşin ko arun ba ọ, nigbati ogun rẹ wa ni arọwọto rẹ. Ẹgbẹrun pere ni (3d) Ẹdẹgbarun fun mejila (2/3d a dozen).

A si ni ipari olorun amu irun dara daradara, o si ma njẹ ki irun sunmọ, o si njẹ ki o ma kọmọna bi jigin, ari malele pada ẹhin. (*Hair preparations.*)

Kọwe tabi bere l'ọdọ
DIPO TUNDE & Co,
P.O. Box 335,
30, Victoria Road
Lagos, Nigeria

---

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo oja si Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo oja na ka.

---

*Ibi ni ẹnyin ro si mi—Şugbọn Oluwa mọ si rere*

OKANLAWON BALOGUN BROTHERS

Dealers in best quality of Produce viz:—Cocoa, Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc.

*Head Office* :—16, BANKOLE STREET, Lagos.

*Branches at* :—Lagos, Agege, Agbado, Ilọ, Wasinmi, Owowo, Ibara, Lafe, Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun, Oshogbo.

*A trial order will be thankfully solicited.*

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.